AWON OHUN PATAKI
NINU IOE OSE YI
Zik di odun mokanl·i dota
Oju iwe 1
Adegoke Adelabu firi ejo
Oju iwe 1
Adeniran Or·n re o
Oju iwe 2
Ibinu ki i mu re wa
Oju iwe 3

# IRAHO ★ OBOKUN

Oro Oye Asogbe
Oju Iwe 4
Fi oruko sile fun idibo
Oju iwe 5
Ajodun ikoze
Oju iwe 6
Oro yi ko ye mi
Oju iwe 7
Agbegilodo mabera Epo
Oju iwe 8

Vol 4 No 163 ILESHA MONDAY NOVEMBER 21 1955 IYE OWO: TORO

# OBABIRIN ILE GESI, OKO ATI AWON OMO RE YIO BE NIGERIA WO



(HER MAJESTY) ỌBABIRIN ELIZABETH KEJI

Lati nkan bi oṣu kan sehin ni ikede ti jade lati Afin Buckingham pe Alaiyeluwa Ọbabirin Elizabeth Keji yio bẹ Nigeria wo ninu oṣu kini ọdun to mbọ. Igbimọ alaṣẹ ijọba ti Ẹkun Ila Orun ti pinu lati na owo to ju £35,000 fun igbokegbodo ti ibẹwo Ọba na ati awọn ẹmẹwa rẹ. Ijọba ti Ẹkun Ariwa na ti yan Kọmiti mẹwa lati ṣeto lori gbigba Ọbabirin na ati awọn ẹmẹwa rẹ ni alejo.

## ỌNI IFẸ ṢE AJỌDUN KARUNDỌGBỌN OYE

Ni ọjọ karundogun nṣu yi ni Ọni Ifẹ, Ọba Adeṣoji Aderẹmi keji ṣe ajọdun karundọgbọn to ti gori oye gẹgẹbi Ọba Ifẹ.

Lati ọsẹ kan ṣaju ọjọ na niwọn ti ta aṣọ funfun si awọn ẹnu odi abawọla Ifẹ, ti wọn si ṣe ikeda ajọdun na sara awọn aṣọ na.

Lọjọ iṣajọdun na, Ọba Aderẹmi sọ pe o dun mọ on ninu pe kosi rogbodiyan larin gbogbo ọjọ ti on ti wa lori oye. O ni afi awọn ohun alafia ati itẹsiwaju to nwọlu.

AKỌLE OLOTU:- Ki Ọlọrun ṣe iyoku igbesi aiye ọba na ni ti alafia ati itẹsiwaju.



.DR. NNAMDI AZIKIWE

O ti di eni ọdun mokanleladọta ni ọjọ kerindinlogun osu yi. Yio ti ilu Oyinbo de Eko lojo kokandinlogun osu yi, yio de Ibadan logbonjo osu yi. Yio de Ilesa lojo kini osu to mbọ.

## AZIKIWE D'ỌMỌ ỌDUN MỌKANLELADỌTA

Ni ọjọ Wednesday, ọjọ kerindinlogun osu yi ni Dr. Nnamdi Azikiwe, di ọmọ ọdun mọkanleladota.

Wọn bi Ọlọla nani ọjọ kerindinlogun oṣu kokanla ọdun 1904 ni Zungeru ni Oke Ọya.

Ọpọlọpọ ilu ni wọn ti ṣe ọjọ ibi Ọlọla na lojo na jake jado Nigeria. On na wa ninu ọkọ ninu irin ajo rẹ lati London lọjọ ibi rẹ na.

Dr. Nnamdi Azikiwe ni Baba Ẹgbẹ NCNC jake jado Nigeria ati Kamerums. On ni Olori awọn Olusetọ ijọba Ẹkun Ila Orun Nigeria.

Lati ọpọlọpọ ilu ni wọn ti nki ku orire ti ọjọ ibi rẹ.

## ỌLỌLA ADEGOKE ADELABU BỌ NINU ẸJỌ KAN

Lati ẹhin igbati wọn ti joye Olubadan ilu ni wọn ti fi esun ẹjọ kan Ọlọla Adegoke Adelabu ati awọn mẹjọ miran pe wọn da ilu ru, wọn pa enia lara ati pe wọn mọ-mọ ba ohun ini elomiran jẹ.

Ọlọla Dingle Foot, ọkan ninu awọn Amofin ti Ọbabirin Ilẹ Gesi da lọla, lo ṣe agbẹjọro fun Adelabu ati awọn yoku.

Niwaju Adajọ Agba ti ẹkun Iwọ Orun Nigeria, Ọlọla Ọmọba Adetokunbọ Ademọla ni won ti gbọ ẹjọ na ni kotu nla Ibadan.

Ọlọla Adegoke Adelabu, Asani Akinyọ, Salani Adeyemọ, Muyibi Akanbi, ati Amusa Ojutayo ko jẹbi rara ninu awọn ti wọn fesun kan.

Awọn mẹta to jẹbi ti san owo ti wọn fi jẹ wọn niya:

# IJESHA DIVISIONAL COUNCIL

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited from reliable registered Contractors for the construction of the following at Ilesha:—

(1) GARAGE.

(2) LATRINES (2)

2. Tenders must be submitted in sealed envelopes marked at the right top corner "Tender for Garage or Latrine" as the case may be and addressed to the Secretary, Ijesha Divisional Council, Ilesha to reach him not later than 2 p.m. on 2nd December, 1955.

3. Plans and Specifications are available for inspection at the Office of the Supervisor of Works, Divisional Council Works Yard, Ilesha.

4. The Ijesha Divisional Council is not bound to accept the lowest or any tender.

**(Sgd.) M. A. Akinwumi.**
Secretary,
Ijesha Divisional Council.

## ỌBABIRIN GẸSI YIO BẸ NIGERIA WO

Lati nkan bi oṣu kan sehin ni wọn ti fi ikede sode lati Afin nla ti London pe Ọbabirin Her Majesty Queen Eliz beti keji yio bẹ Nigeria wo ninu oṣu kini ọdun to mbọ yi.

Ọkọ rẹ, (His Royal Majesty) Alaiyeluwa Lọja ilu Edinburgh ati awọn ọmọ rẹ (Their Royal Highness) Ọmọba Charles ati Ọmọbabirin Anne yio pẹlu rẹ bẹ Nigeria wo.

Lati igbati ikede na ti jade ni awọn ijọba Nigeria ti nṣe imurasilẹ nitoripe gbogbo awọn ijọba na ni yio bẹwo ni ikorita eto iṣẹ wọn.

Ẹniti o jẹ akọwe agba fun ijọba akopọ Nigeria ti lọ si ilu ọba lati lọ dabun si oriṣiriṣi ibere to le ti Afin Ọba Gesi jade lori aye to le wa fun gbigba Ọba na ati awọn ọmọ rẹ lalejo.

## GOMINA ATIJỌ YIO ṢOJU ILẸ GẸSI

Sir John Macpherson, ẹniti o ti jẹ Gomina apapọ Nigeria ri ni yio ṣe aṣoja ijọba Gesi ni igbimọ ipade ẹgbẹ alasowọpọ gbogbo agbaiye (United Nations Visiting Mission).

Gbogbo awọn to ba jẹ aṣoju ninu igbimọ ibẹwo na yio de gbogbo awọn orilẹ ede ti wọn nba ṣeto ijọba loruko apapọ ẹgbẹ nla na.

# FA OGBON YO

## OKUNRIN Ẹ FEYI SỌGBỌN

Lati ọwọ B. A. Fatumubi 8 Laro St Oshogbo

Eyi si npoju ka fẹ iyawo ki a ma ni ikan abo, eyi si npo.

Idunnu ni pupọ fun im, ti a ba ronupiwapa nipa asansantan owo ori obirin ni ilu Oṣogbo yi St. a ba ba ọran wi ki a si ma gbagbe lati ba ọran wi. Idi eyi ni wipe nhoto ni awọn ọmọbirin wa ni ọkanjuwa, ṣugbọn awa ni a nje ara wa.

Ọrẹ meji nfẹ obirin ni agbole kanna, ekini lowo ekeji kosi nwọn fẹ sanwo ori aya, (£25) Poun medọgbọn tani ara yio nijuʔ Papa, ẹfi ti owo ajọ ọsọọṣẹ bere, sile marun, eyi si npoju.

Ẹ ranti wipe nkan tọ wa lẹhin ọfa ju oje lọ. A le fẹ obirin kan ki ati jẹun dọran bi?

Mo bẹ ẹnyin ọkunrin ika ọwọ ko dọgba. Papa ti a ba ronu si nkan ti awọn obirin nfi oj[a] wa ri nipa owo ori, owo Ẹbu[a] ati idawo ọsọọṣẹ, ti a ko b[a] ni alafẹbinti, nje gbajumọ kon[1] jale bayiʔ

Fun idi eyi, mo bẹ ẹnyin obi awọn ọmọge wa papa ẹnyin ti ẹ ni ọmọkunrin ti ẹo gbeyawo fun ẹnyin papa mọ iru nkan ti yio bọ ni apo yin. ju gbogbo rẹ lọ, ere loje, ṣugbọn a san ogun, a sin ọgbọn, a ṣe isiro gbogbo nkan wọnyi, o jẹ adọjọ poun (£150), o wa to igbati aya ma wọle, o ba ẹlomiran salọ, wọn si ma dajọ ni ile ifajọ ọrẹ mi wọn ni lori gbogbo nkan to san ko gba poun mẹdọgbọn (£25) laisiro erirun nkan toku

Ha! ha'ọ kita ko mani koko. Ẹ ronu si iwa ika yi.

# IRAWO OBOKUN FUN ERINMO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lati ra rawọ Obokun ni Ẹrinmọ ati agbegbe rẹ ki o bere lọdọ Ọgbẹni Samuel O. Ogundele Ọna Ẹffọn No 644 Ẹrinmọ.

## S. A. ADENIRAN ỌRUN RERE O

(Lati Owọ Ọgbẹni I. F. Ọpẹsuṣi Goast Colony)

Ni idupẹ gidigidi fun aye soki ti ẹo gba mi ninu iwe irohin nyin ti ilẹ wa ti nṣe Irawọ Oboku ni ede Yoruba. Mo ki ẹbi, ọmọ, aya, ọrẹ aya, aladugbo, Alaiyeluwa Ọba Ọwa ti Ilẹ Ijẹṣa ti nṣe Baba fun Ọlọla Ologbe Ọmọ'ba S. A. Adeniran, awọn Ijoye Ileṣa ati ti agbegbe, l'ọkunrin ati lobirin, Ijọ Ọtapete ti nṣe ile isin ti Ologbe yi ni igba aiye rẹ ati gbogbo Ijẹṣa lapapọ.



ỌGBẸNI I. F. ỌPẸSUSI

O kọwe lẹta yi lati de Gold Goast ni ibanẹdun iku Ọmọ'ba S. A. Adeniran: O kẹdun nipa iku Ọgbẹni Joseph Ajayi Tẹniọla pẹlu.

Papa Alagba E. A. Kayọde ti nṣe Ajirọba Baba ati korikosun Ọlogbe yi nigba aiye rẹ.

Baba J. F. Longẹ, Alaga Ẹgbẹ Atunluṣe ti Ilẹ Ijẹṣa, eyiti Ologbe yi jẹ ọkan pataki ati amuludun ni ile Ijẹṣa, Ki Ọlọrun ki o ma salaigbe si afẹfẹ rere, ki o fi isọ rẹ sọ awọn enia rẹ ti o fi silẹ lọ jẹ ipe Olodumare.

Ọrun rere o, Ọmọ Ọba S. A. Adeniran mi ọwọn, Ọga ati iyekan mi pataki nigba aiye rẹ.

Niwọn ọjọ mẹta ti irohin ọfọ yi de eti igbọ wa nihin a kole sun. Bi mo ti nsun, bẹni mo nri ni oju ala ti o nbami sọrọ pataki-pataki orisirisi gẹgẹ bi iṣe rẹ simi nigba aiye rẹ. (How Are The Mighty Falling) Ẹ wo bi awọn alagbara ti nṣubu.

Ah! Ah! Ah! Ọmọ Aromọlọran,
Otutu bi ọsun, Arojojoye,
O dele tejiteji, Ọmọ Oṣupa Ilẹki
A mọ roro ninu agba
Ọrun rere o.
Ki o ma jọkun ki o ma si jekolo,
Ohun ẹlẹmọ ba nje lode ọrun ni ki o ma jẹ o.
Ipade di ọjọ igbende
Aṣọṣọba ni gẹgẹ ja lẹhin
Oloke ẹnkuja yun,
A bijọ gbogbo bi ọdun.
Ọrun rere o.

Mo tun bẹbẹ bẹ gẹgẹ lati mu aye yi lo tan ki awọn ẹbi, ọrẹ ati gbogbo Ijẹṣa pe awọn tun ku afẹku olori ẹgbẹ Irawọ Gbajumọ Club, Joseph Ajayi Tẹniọla papa awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ lapapọ.

Ọlajide Adelusi ati Samuel Oni Ogunmọdẹde ti nwọn di ologbe nipa iku ewu moto. Ki Ọlọrun ki o forun kẹ wọn o. Lọwọ iku ojiji ki Oluwa rere gba wa.



ỌMỌ'BA ADE ADEYOKUN

On pẹlu awọn oluko ti a le pe ni oluko atọrun wa nitoripe o pẹlu awọn to kọ eyi ti o pọju ninu awọn ọmọwe ode oni ni ilẹ Ijẹṣa. Akọle Olotu ọsẹ yi ṣe akiyesi pe awọn ile iwe yoku lati ni ile ikawe fun ile iwe wọn.


Advert Donated by IRAWO OBOKUN

# ILESHA COMMUNITY CENTRE

"BRAINS TRUST"

In pursuance of the informal educational activities of the above Centre "Brains Trust" will come up on Thursday 24th November, 1955 at the Centre, (Old Post Office) at 5. 30 p. m. under the auspices of Ilesha Community Association

2. Questions will be based on Contemporary events and current affairs.

3. The panels of experts in the Brains are:-
Mr. A. F Meed - District Officer Ilesha.
Mr. J. A Akinyẹmi - Principal Grammar School Ilesha
Mrs. A. Adeshigbin - Principal W. T. C
Mr. G. E Udom - Agric Superintendent.

The Question master will be Mr. E. A Adeniyi.

4. You and your friends are all cordially invited to Attend. Admission is free.

5. Please be at your seats by 5. 15 p. m as there are limited number of seats.

**Advisory Management Board Inaugural Meeting**

We are all aware of the existence of a Community Centre in Ilesha organised by the Ilesha Community Association for the promotion of the well-being of the Community resident in Ilesha.

In order to be able to carry on at its objectives in a democratic way it has come to a stage to set up an Advisory or Management Board whose main concern would be principally to associate with the local authorities voluntary youth and advent organisations and all residents in a common effort to further health, to advance education, to provide a meeting place and facilities for physical and mental training and recreation and social, moral and intellectual development and to foster a Community spirit for the achievement of these and other such purposes as may by law be deemed to be charitable. It will also concern itself with the establishment, maintenance and management of a Community centre for activities promoted by the Neighbourhood Association or affiliated organisations and its constituent members.


(Continued page 4)

# IROHIN LATI AGBEGBE

## IJỌ JOHANU MIMỌ TI IDOMINASI ṢE IKORE

(Lati Ọwọ S. O. Ajumọbi, Idominasi)

Ni ọjọ kẹtalelogun oṣu October ni Ijọ Johanu Mimọ C. M S Idominasi ṣe ọdun Ikore.

Nigbati ọdun ikore yi ti ku nkan bi ọsẹ meji ni gbogbo awọn ara ilu Idominasi ti nkun ọdun na kakiri ibi gbogbo, ṣugbọn nigbati o di ọjọ Satide ti i ṣe ọjọ kejilelogun oṣu October ni ọdun na ti wọle nitoripe ko si ẹniti o ri aye sun lati ọjọ na titi di ọjọ keji ọjọ ọsẹ ti i ṣe ọjọ ọdun Ikore gan.

Ni dede agogo mẹjọ abọ arọ, ọjọ ọsẹ ti i ṣe ọjọ ikore yi ni gbogbo ọsẹ awọn ti o fẹ sami ti pe si Ile Ọlọrun (Church). A bẹrẹ isin isami ni dede agogo mẹsan orọ. I y e awọn ti o sami lọjọ na jẹ mọkandinlogun.

A dupẹ pupọ lọwọ alufa wa, Ẹni Ọwọ M. A. Oroge fun ọrọ iṣiri rẹ ti o fun gbogbo enia papa julọ awọn ti a yọyẹ sami fun lakoko igbati a nṣe isin isami na lọwọ. Irugbin ọrọ na ki Ọlọrun jẹ ki o bọ si ilẹ rere lọkan wa o Amin.

Nigbati odi agogo mẹwa abọ orọ, isin ọdun ikore bẹrẹ. A dupẹ lọwọ awọn ẹgbẹ akọrin wa ti nwọn fun wa ni orişirişi orin aladun. Ẹgan ni bẹ, ki Ọlọrun mu ọsẹ awọn ọmọ wa duro ninu ilẹ rere o.

A dupẹ pupọ na lọwọ alufa wa Ẹni-Ọwọ M. A. Oroge fun ọrọ iṣiri rẹ lakoko iwaasu, adura mi ni pe ki Ọlọrun le jẹ ki irugbin ọrọ rere rẹ le so eso rere larin Ijọ wa.

A si tun dupẹ pupọ pẹlu lọwọ awọn ọrẹ wa lati inu Ijọ gbogbo larin ilu wa ni Idominasi ati lati Ileṣa, Ora, Kajọla, Oṣogbo ati lati agbegbe wa fun aṣeyẹ ọ j ọ na. Adura mi nipe ki Ọlọrun jẹki o yẹ awọn na kalẹ Amin.

A si tun dupẹ pupọ pẹlu lọwọ awọn Ẹgbẹ Ọmọlere (ẹgbẹ Lydia Iyalode), fun aṣeyẹ ijọ ti nwọn jo fun ọdun Ikore yi lati ọjọ ọsẹ ti i ṣe ọjọ ọdun Ikore gan titi ilẹ fi mọ nijọ keji.

A si tun dupẹ na lọwọ awọn agbagba Ijọ C. M S, ẹgbẹ ilẹ Mọnia Rosẹgbẹ, ẹgbẹ Aṣiribo ile Mọnija Dapọ ati gbogbo awọn olufẹ Ijọ C M S ti nwọn ba wa ṣe aṣeyẹ ọdun Ikore yi ni ọjọ Mọnde, ọjọ keji ọdun Ikore laiyọ ẹsẹ lọ si oko tabi si odo.

Owo idupẹ ọdun Ikore na jẹ ilọpo meji abọ ti esi. A dupẹ lọwọ Ọlọrun fun itẹsiwaju ati iyipada ti o wa larin Ijọ wa ni ọdun yi.

Ẹnyin Ijọ C M S Idominasi, mo ba nyin yọ fun itẹsiwaju nyin larin Ijọ yi lọdun yi, iwaju ni ẹ o ma tẹsi o, Ọlọrun ko ni jẹki ẹ rẹ ẹhin mọ o. Amin.

AKỌLE OLOTU:- A koni gbe iwe yin jade lọjọ miran ti ẹ ba kọ tinu tẹhin. Ẹ ṢE O.

## "Ẹ GBE AKUKỌ GA"

(Lati Ọwọ S. Ọla. Adeniyi, NCNC Field Secretary, Ileṣa)

Emi Ọlatunji Adeniyi dupẹ pupọ lọwọ Olotu Irawo Obokun.

Ẹnyin Mẹkunnu, ẹnyin Agbẹ ati ẹnyin Aṣanwori ni ile Karọ-jire yi, ẹ fi oruko sile lati le dibo lọdun to mbọ ki ẹ la gbe ẹgbẹ Alakukọ ga!!

Iba ti dun to, ti a ba le faramọ Akukọ dibo? O wa yẹ ka da si ọ Akukọ bi?

Kiala, igbimọ awọn Ọlọpẹ ko le rọ wa lọrun. Nwọn fẹ ku wa ṣuku ṣuku, Ẹ jẹ ka sọ otọ ọrọ fun ra wa. Iwa ododo tabi otitọ jinna si eni to nforibalẹ f'Ọlọpẹ bi oriṣa

Ẹ lọ fi oruko silẹ lati dibo lọdun to mbọ (1956) fun ẹgbẹ Alakukọ.

Ẹ jinna si awọn Ẹgbẹ Onisowo ile Yoruba ki o ma di agunla fun emi tirẹ,

## OWOẸYẸ NI ẸRINMỌ DIBO FUN

(Lati ọwọ S. T. Ogundele)

Inu mi dun lati ki awọn ọmọ Ẹrinmọ ti wọn dibo fun Ẹlẹrinmọ ti Ẹrinmọ Ogbẹni Owoẹyẹ Asede ti o wọle, mo si dupẹ lọwọ Ẹlẹrinmọ ti Ẹrinmọ pe o ku ṣuru o ku aini ibaraje.



S. T. OGUNDELE

Mo ki i gidigidi ko pọn omi oke ru lodo, ko si pọn omi odo ru toke. Inu mi dun nigbati mo gbọ pe o ti wọle.

Ẹnyin ọmọ Ẹrinmọ a ti ni Ọba ki Oluwa jẹki o pẹ fun wa o. Owoẹyẹ dara l'ọba Ẹrinmọ, ẹ o ri ko ga ju ko si kuru ju,

Bi o ba ri ọmọde, inu rẹ a ma dun, a si ma ẹrin si. O ma aba ọmọde ṣere. A si ma ki agba tẹriniẹrin, O ma buyi fun agba.

Ẹnyin ọkawe Irawọ Obokun ẹ bawa gbadura fun Ẹlẹrinmọ Asede ti o jọ ọba si ilu Ẹrinmọ pe ki Ọlọrun jẹki igba tirẹ dara fun wa amin.

Mo dupẹ lọwọ ẹniti o ṣe irohin nipa oye Ẹlẹrinmọ ti Ẹrinmọ eyiti o jade ninu Irawọ Obokun ti September 26th 1955.

Co lo dupe lọwọ awọn to fara mọ Ọgbẹni Owoẹyẹ nibi iwadi oye ti Ẹlẹrinmọ. O ni Ọgbẹni na ni gbogbo ara Ẹrinmọ lẹ ki o jẹ oye Ẹlẹrinmọ.

Oluwa rẹ ṣe olotitọ enia ọjọ ti Ajẹlẹ agba ti Ọyẹ wa si Ileṣa ni mo ti gbọ ni Ibadan mo si ti gbọ gbogbo irohin iwadi ti Ajẹlẹ wa ṣe.



ỌGBẸNI D. O ỌṢUNLOYE

On ni olori awọn oluko ile iwe Oke Oye bayi. Wọn sọpe on lo jẹki eto idasilẹ ile ikawe fun awọn ọmọ ile iwe Oke-Oye ni iyọri. Awọn eleto ile iwe na nbẹbẹ fun ironiọwọ awọn obi ati awọn olufẹ lati fi owo ati iwe ọlọgbọn ran wọn lọwọ.


## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inşi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| igba | 1—12 | 5s | fun inşi kan |
| igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| gba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inşi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

